# AWỌN AMÍ MEJILA ATI IROYIN WỌN

## Numeri 3:1-33; Deuteronomi 1:19-24

### ẸKỌ 101 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori ẹniti o ba nfunrugbin sipa ti ara rẹ, nipa ti ara ni yio ká idibajẹ; ṣugbọn ẹniti o ba nfunrugbin sipa ti Ẹmì, nipa ti Ẹmí ni yio ká ìye ainipẹkun" (Galatia 6:8).**

**I Aṣẹ Oluwa lati Lọ Ṣe Amí Ilẹ Kenaani**

1. O paṣẹ fun Mose lati rán ijoye kan ninu ẹya kọọkan lati lọ wo ilẹ naa, Numeri 13:1, 2
2. Mose yan ijoye mejila, eniyan kan ninu ẹya kọọkan, lati ṣe amí ilẹ naa, Numeri 13:3-15
3. Ninu wọn ni Kalebu ti ẹya Juda, ati Joṣua ti ẹya Efraimu wa, Numeri 13:6, 16

**II Ijọ Eniyan fẹ Ki Awọn Aṣayan Ọkunrin lọ Ṣe Ami Ilẹ Naa**

4. Israẹli la aginju nla ti o kun fun ẹru kọja lẹyin ti wọn kuro ni Horebu (Oke Sinai), Deuteronomi 1:19
5. Wọn de oke awọn ọmọ Amori, a si gba wọn niyanju lati gba a, Deuteronomi 1:20, 21
6. Ṣugbọn ijọ eniyan bẹ Mose lati rán awọn ọkunrin lọ wo ilẹ naa ṣiwaju wọn, Mose si ṣe bẹẹ, Deuteronomi 1:22-24

**III A Fun Awọn Amí Mejila ni Itọni Kikún**

7. Mose paṣẹ fun wọn lati mọ bi awọn eniyan naa jẹ alagbara tabi alailagbara, bi eniyan pupọ ni wọn tabi diẹ, Numeri 13:17, 18
8. A paṣẹ fun wọn lati mọ bi ilẹ naa dara tabi ko dara; bi ilu, agọ tabi ilu-olodi ni, Numeri 13:19
9. O sọrọ ti yoo ki wọn laya, o si sọ fun wọn ki wọn ki o mu eso ilẹ naa wa, Numeri 13:20

**IV Awọn Amí Mejila ṣe Oloootọ ninu Iṣẹ Wọn**

10. Wọn rin ilẹ naa lati Sini ni iha guusu lọ si Hebroni ni iha ariwa, Numeri 13:21, 22
11. Wọn mu ìdì èso ajara wá lati Eṣkolu, ti eniyan meji rù, ati eso pomegranate ati ti ọpọtọ, Numeri 13:23, 24
12. Wọn pada bọ̀ lẹyin ogoji ọjọ ti wọn ti lọ rin ilẹ naa wò, Numeri 13:25

**V Iroyin Awọn Amí Mejila fun Awọn Ọmọ Israẹli**

13. Wọn jihin pe dajudaju ni ilẹ naa "nṣàn fun wara ati fun oyin," wọn si fi eso ibẹ hàn, Numeri 13:26, 27
14. Wọn royin pe awọn eniyan naa lagbara, wọn si n gbe inu ilu olodi, Numeri 13:28, 29
15. Kalebu pa awọn eniyan lẹnu mọ́, pe, "Ẹ jẹ ki a gòke lọ lẹ̃kan, ki a si gbà a," Numeri 13:30
16. Ṣugbọn awọn mẹwaa mú iroyin buburu wá, wọn tẹnu mọ ọn pe awọn omiran alagbara ni o n gbé ilẹ naa, Numeri 13:31-33

## ALAYE

**Israẹli dé Ẹba Kenaani**

Lẹyin ti a ti fi Ofin fun Israẹli ti a si ti fi idi eto ijọsin ninu Agọ mulẹ tan, awọn Ọmọ Israẹli fi Oke Sinai silẹ, ọwọn awọsanma si ṣe amọna wọn taara lọ si ẹba Ilẹ Ileri. Gẹgẹ bi awọn eniyan yii ti mọ̀ tẹlẹ, OLUWA ṣe ileri lati fi ilẹ yii fun Abrahamu ati iru ọmọ rẹ. Ọlọrun ṣe apejuwe rẹ bi "ilẹ ti o nṣàn fun wara ati oyin." Bakan naa ni O mu awọn Ọmọ Israẹli jade lati ilẹ Egipti, ki i ṣe lati dá wọn silẹ kuro ninu isinru awọn ika akoniṣiṣẹ wọn nikan, ṣugbọn ki O le mu wọn wá si ilẹ ọlọra yii nibi ti wọn yoo gbe ni ọgbà ajara ti wọn ko gbin ati ilu ti wọn kò kọ́ tikara wọn. Nitori idi eyi, nigba ti wọn de oke awọn ọmọ Amori, ni iha guusu Kenaani, Mose wi pe, "Wò o, OLUWA Ọlọrun rẹ ti fi ilẹ na siwaju rẹ: gòke lọ, ki o si gbà a, bi OLUWA, Ọlọrun awọn baba rẹ ti wi fun ọ; máṣe bẹ̀ru, bẹ̃ni ki àiya máṣe fò ọ" (Deuteronomi 1:21). Lai si aniani awọn Ọmọ Israẹli ti ni iṣiri tó lati lọ gba ilẹ naa lẹsẹkẹsẹ.

**Eto Israẹli lati Rán Ami**

Ṣugbọn awọn Ọmọ Israẹli, ninu irin-ajo wọn lati Oke Sinai wá, ṣẹṣẹ la "aginjù nla nì ti o ni ẹ̀ru já" ati "òke awọn ọmọ Amori" nibi ti o lẹru ti awọn eniyan ibẹ si ya ẹhànnà loju wọn. Nitori naa wọn sọ fun Mose pe, "Jẹ ki awa ki o rán enia lọ siwaju wa, ki nwọn ki o si rìn ilẹ na wò fun wa, ki nwọn ki o si mú ìhin pada tọ̀ wa wá, niti ọna ti a o ba goke lọ, ati ti ilu ti a o yọ si" (Deuteronomi 1:22). Nipa eyi, a le ri i pe awọn Ọmọ Israẹli ko gbẹkẹ le ọwọn awọsanma naa lati ṣe amọna wọn si Ilẹ Ileri, bi o tilẹ jẹ pe OLUWA Ọlọrun wọn ti ṣeleri tẹlẹ lati lọ ṣiwaju wọn lati jà fun wọn (Deuteronomi 1:30). Ju gbogbo rẹ lọ, wọn fẹ mọ daju boya tootọ ni ilẹ Kenaani jẹ ilẹ ti o lọra gẹgẹ bi a ti wi fun wọn tẹlẹ, bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun paapaa tikara Rẹ ti sọ fun wọn pe "ilẹ ti o nṣàn fun wara ati oyin" ni ilẹ naa i ṣe.

**Aigbagbọ Israẹli**

Ẹ wo bi awọn Ọmọ Israẹli ti yatọ si Abrahamu baba wọn to! Gbogbo ohun ti Ọlọrun sọ ni o gbagbọ́. Gbogbo aṣẹ Ọlọrun ni o si gbọran si. Nigba ti Ọlọrun wi fun un pe, "Jade kuro ni ilẹ rẹ, ati kuro lọdọ awọn ara rẹ, ati kuro ni ile baba rẹ, si ilẹ kan ti emi o fi hàn ọ," lẹsẹ kan naa Abrahamu ko awọn ara ile rẹ jọ, "nwọn si jade lati lọ si ilẹ Kenaani, ni ilẹ Kenaani ni nwọn si wá si" -- ilẹ ti oun ko mọ ri. A mọ Abrahamu ni orukọ ti o yẹ ẹ, ani "baba igbagbọ." O rìn nipa igbagbọ́, ki i ṣe nipa riri; nitori a kọ ọ pe, "Olododo yio yè nipa igbagbọ́," ati pẹlu pe, "Li aisi igbagbọ́, ko ṣe iṣe lati wù u." Awọn Ọmọ Israẹli kò tẹle apẹẹrẹ rere ti igbagbọ baba wọn. Lai si aniani, wọn ro pe eto ti o dara pupọ ni lati rán amí jade. Wọn ro pe eyi yoo ṣe iranwọ fun wọn lati ṣẹgun awọn ọta wọn. Ṣugbọn eyi ki i ṣe eto OLUWA Ọlọrun baba wọn. O ti paṣẹ pe, "Gòke lọ, ki o si gbà a." Igbekalẹ eniyan ninu eyi ti a kò fi ti Ọlọrun pè yoo já si asán.

Ẹṣẹ awọn Ọmọ Israẹli ti o tobi ju lọ ni aigbagbọ. Ẹṣẹ yii ni o n kó wahala ba wọn nigbakuugba ninu aginju. Ọkan aigbagbọ ni o fa kikun ati irahun wọn. O mu ikuna ba wọn lera-lera, nihin yii pẹlu a o ri i pe eyi mu ki awọn iran ti o dagba kuna lati wọ ilẹ ileri. Ẹṣẹ buburu yii ko si pin si igba Ofin ati awọn wolii nikan. Episteli si awọn Heberu jẹ ikilọ fun awọn Onigbagbọ Heberu nipa ikuna awọn baba wọn lati wọ inu isinmi wọn. Wọn di ọmọlẹyin Jesu Kristi Oluwa gẹgẹ bi Messiah wọn; fun iwọn igba diẹ wọn fi tayọtayọ gba lati padanu ohun ini wọn, ṣugbọn nigba ti inunibini ati ipọnju ko dẹkun, nipa aigbagbọ ati aarẹ ọkan, wọn wá sinu ewu iṣubu kuro ninu ireti wọn ninu Kristi Jesu. Ninu ori kọkanla Episteli yii, ẹni ti o kọ iwe naa mu awọn akọni wọnni ninu awọn baba wọn wá si iranti wọn, ẹni kọọkan wọn ẹni ti o ṣẹgun nipa igbagbọ́. Bi ohun gbogbo si ti wa ko ti i yi pada. Ni ode-oni, ẹ̀ṣẹ ti o buru ju sibẹ ni aigbagbọ. A si le ri ẹkọ kọ́ nipa fifi ohun ti o de ba awọn Ọmọ Israẹli si iranti. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ pe, "Ninu aiye, ẹnyin o ni ipọnju; ṣugbọn ẹ tujuka; mo ti ṣẹgun aiye" (Johannu 16:33).

**A Yan Amí Mejila**

Bi o tilẹ jẹ pe eto awọn Ọmọ Israẹli lati rán awọn eniyan ṣaaju wọn lati lọ ṣe amí Ilẹ Ileri, ko dun mọ Ọlọrun, sibẹ O gba fun wọn nitori wọn beere fun un, O si wi fun Mose pe, "Rán enia, ki nwọn ki o si ṣe amí ilẹ Kenaani, ti mo fi fun awọn Ọmọ Israẹli" (Numeri 13:2). Gẹgẹ bi Ọlọrun ti paṣẹ, Mose yan ẹni kan lati inu ẹya kọọkan, olulukuluku "jẹ́ ijoye ninu wọn," Joṣua lati inu ẹya Efraimu ati Kalebu lati inu ẹya Juda wà pẹlu wọn, a si rán wọn lọ lati wo ilẹ Kenaani, a si wi fun wọn pe, "Ẹ gbà ọ̀na ìha gusù yi, ki ẹ sì lọ sori òke nì; ki ẹnyin si wò ilẹ na, bi o ti ri; ati awọn enia ti ngbé inu rẹ̀, bi nwọn ṣe alagbara tabi alailagbara, bi diẹ ni nwọn, tabi pupọ̀; ati bi ilẹ na ti nwọn ngbé ti ri, bi didara ni bi buburu ni; ati bi ilu ti wọn ngbé ri ri, bi ninu agọ́ ni, tabi ninu ilu odi" (Numeri 13:17-19). Mose si paṣẹ fun wọn pe, "Ki ẹnyin ki o si mu ọkàn le, ki ẹnyin si mú ninu eso ilẹ na wá."

Awọn amí mejila wọnyii mú ọna ajo wọn pọ̀n lati Kadeṣi-barnea ni iha guusu titi wọn fi de Hebroni nibi ti Abrahamu, baba wọn, ti ṣe atipo ri. Nihin yii ni Abrahamu gbe joko labẹ igi oaku ni Mamre nigba ooru ọjọ, ti o si ṣe awọn ọkunrin mẹta ni alejo ninu agọ rẹ̀, nikẹyin ti o si mọ pe angẹli ni oun ṣe loore. Boya ni igba ewe wọn, awọn amí wọnyii ti gbọ itan yii ninu ile nipa baba wọn ti o jẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun, wọn si mọ pe ilẹ mimọ́ ni wọn duro le lori. Gbogbo Kenaani ti di "Ilẹ Mimọ," nitori nibẹ ni Ọlọrun gbe ba awọn baba nla wọn pade. Awọn iṣẹlẹ mimọ́ wọnyii ni lati rú ifẹ awọn Ọmọ Israẹli soke lati bọwọ fun Ọlọrun ti o fi ilẹ yii fun wọn ki wọn si gbọran si I.

Irin ajo diẹ siha ariwa Hebroni ni awọn amí gbà wọ afonifoji Eṣkolu, wọn si ri idi eso ajara nla nì ti wọn rẹ́, wọn si gbé e wá, awọn eniyan meji si fi ọpa rù ú. Wọn mu eso ọpọtọ ati pomegranate bọ̀ pẹlu lati fi hàn pe ni tootọ eyi jẹ́ "ilẹ ti o nṣàn fun warà ati fun oyin."

**Iroyin Awọn Amí Mejila**

Awọn eniyan yii fi ogoji ọjọ wo ilẹ naa finnifinni, wọn si mú eso rẹ̀ wa, wọn ṣe tan lati ṣe iroyin ohun ti wọn rí. Wọn si wi fun Mose ati Aarọni, ati fun gbogbo ijọ awọn Ọmọ Israẹli ni Kadeṣi pe "Awa dé ilẹ na nibiti iwọ gbé rán wa lọ, nitõtọ li o nṣàn fun warà ati fun oyin; eyi si li eso rẹ̀" (Numeri 13:27).

Bi OLUWA ti wi gan an ni o ri – "ilẹ ti o nṣàn fun warà ati fun oyin." Ṣugbọn wọn ri ohun miiran pẹlu. "Ṣugbọn alagbara ni awọn enia ti ngbé inu ilẹ na, ilu olodi si ni ilu wọn, nwọn tobi gidigidi: ati pẹlupẹlu awa ri awọn ọmọ Anaki nibẹ̀. Awọn ara Amaleki si ngbé ilẹ ìha gusù: awọn ara Kenaani si ngbé ẹba okun, ati ni àgbegbe Jordani" (Numeri 13:28, 29). Kalebu, ọkan ninu awọn amí wọnyii si pa wọn ni ẹnu mọ́ niwaju Mose pe, "Ẹ jẹ ki a gòke lọ lẽkan, ki a si gbà a; nitoripe awa le ṣẹ́ ẹ" (Numeri 13:30). Joṣua gbe Kalebu lẹsẹ, ṣugbọn awọn mẹwaa iyoku ti ó bá wọn lọ wi pe, "Awa kò le gòke tọ̀ awọn enia na lọ; nitoriti nwọn lagbara jù wa lọ" (Numeri 13:31). Bayii ni wọn mú iroyin buburu nipa ilẹ naa wá, wọn si mu ọkàn awọn eniyan fà sẹyin lati ṣe ohun ti OLUWA palaṣẹ, "Goke lọ, ki o si gbà a."

**Asọ̀ Laaarin Awọn Ará**

Lai si aniani, awọn eniyan yii ro pe wọn jare idayafo ti wọn dá silẹ niwọn igba ti o ti jẹ pe awọn alagbara eniyan ni o n gbé ilẹ naa. Ṣugbọn bi a ti n ba ẹkọ wa lọ nipa awọn Ọmọ Israẹli, a o ri i pe kikó irẹwẹsi ba ni ki i ṣe ẹ̀ṣẹ kekere rara. Bi irẹwẹsi ba ti wọ inu ọkàn, iná igbagbọ́ yoo kú; aigbagbọ ni o fa iṣubu awọn Ọmọ Israẹli. Ijaya ni irin iṣẹ ti eṣu n lo lati bi igbagbọ awọn eniyan ninu Ọlọrun wó. O si moke ni lilo irin iṣẹ yii fun awọn Ọmọ Israẹli. Bayii ni awọn amí mẹwaa abẹru wọnyii dá ija silẹ laaarin awọn ará, akọsilẹ idajọ Ọlọrun lori dida ija tabi asọ silẹ wà ninu Ọrọ Ọlọrun.

**"Ohun mẹfa li OLUWA korira: nitõtọ, meje li o ṣe irira fun ọkàn rẹ̀:**
**"Oju igberaga, ète eke, ati ọwọ ti nta ẹ̀jẹ alaiṣẹ silẹ,**
**"Aiya ti nhumọ buburu, ẹsẹ ti o yara ni ire sisa si ìwa-ika,**
**"Ẹlẹri eke ti nsọ eke jade, ati ẸNITI NDÁ ÌJA SILẸ LARIN AWỌN ARAKUNRIN" (Owe 6:16-19).**

## AWỌN IBEERE

1. Apá bebe Kenaani wo ni Israẹli dé nigba ti OLUWA paṣẹ fun wọn lati gba ilẹ naa?
2. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli pinnu lati ṣe nigba ti Mose sọ ohun ti OLUWA wi fun wọn?
3. Amí meloo ni a yàn, ki ni ṣe ti a si fi mọ bẹẹ?
4. Ilẹ awọn eniyan wo ni wọn ti bẹrẹ si i ṣe amí ilẹ Kenaani?
5. Nibo ni wọn dé ni iha ariwa? Ki ni ohun pataki ti o ṣẹlẹ nibẹ?
6. Nibo ni awọn amí gbé ri awọn èso ti o sanra? Ki ni wọn mu pada bọ̀ pẹlu wọn?
7. Ọjọ meloo ni awọn amí fi rin ilẹ Kenaani wò?
8. Irú iroyin wo ni wọ́n mú pada bọ̀? Ki ni wọn wí, ki ni o buru nibẹ?
9. Ki ni ohun ti ọ̀kan ninu awọn amí wọnyii sọ lati doju kọ ihin buburu wọn? Ki ni orukọ rẹ?
10. Ki ni abayọrisi iroyin buburu naa laaarin awọn Ọmọ Israẹli?